ASOJE ORO

[illegible]

# ELETI OFE

A-NJU-WON KO ṢE WI LEJO

O W E

[illegible] Ewure wole [illegible]

VOL. XII No 695. LAGOS SATURDAY OCTOBER 1, — OCTOBER 7, 1960 KOBO MEJI (2D)

# ILE NIGERIA GB'OMINIRA LONI, E MA YO, IRE DE !

## E ku Ayo Ominira

Eniti a nwo ninu aworan yi ni eni-ola nla, Ọmọba Obinrin Alexandra ti o wo ṣ'oju fun Alaiyeluwa Ọba ile Gẹsi gibi ayẹyẹ ayọ isọni-dominira ilẹ Nigeria loni.



Eniti [illegible] Ọmọba Alexandra na ni yio gbe ijọba [illegible] ilẹ Nigeria le Alhaji Sir, Abubakar Tafawa Balewa [illegible].

Ọmọ Nigeria, a ku orire.

## OLOTU IJỌBA NIGERIA



ALHAJI SIR ABUBAKAR

## ỌKUNRIN KAN FI ẸTU OLORO ṢE IDẸRUBA

New York A gbọ irohin wipe ọkunrin Oniyẹyẹ kan gbe apoti ẹrọ gramophone ti o nkọrin dani, bi o ti nlọ larin ilu o ṣakiyesi wipe Ogbeni Eisenhower ti iṣe Baba-ẹgbẹ gbogbo ilẹ Amerika wọ ṣọbu kan lọ, on na si wọ ṣọbu yi pẹlu, o si ri Baba-ẹgbẹ na nibiti o nba enikan sọrọ.

Bẹni o kigbe wipe, kai! e gbe loni ẹtu oloro (Bomb) ni on gbe dani yi, o ku ọna ti ẹo gba lọ. Awọn ara ilẹ Amerika ti nwọn mọ iru ohun ti ẹtu oloro jẹ, larin iṣẹju kan gbogbo ile na ti fọnka ati eniti o nra ati ẹniti o nta. Ọgbẹni Eisenhower paapa ti fẹlẹ.

**THE NATIONAL BANK**
**Of Nigeria Limited**

Incorporated in Nigeria in 1938
Paid up Capital £1,130,000
Banker to the Western Region Government of Nigeria
HEAD OFFICE
37, MARINA, LAGOS NIGERIA.
22, Branches Throughout Nigeria including
IBADAN, ABEOKUTA, IJEBU-ODE,
OSHOGBO, OWO, ONDO, ILESHA
ILARO, BENIN-CITY, WARRI
SAPELE, ABA, KANO, ZARIA, JOS
London Office
1, THROGMORTON AVENUE, E.C. 2.
Manager: F. O. Tyrrell
Telephone: London Wall 4303 — Cables & Telegrams Natbaniger London.
Head Office Representatives in London
E. AKI WUMI DOHERTY
Correspondents
NEW YORK, PARIS HAMBURG.

# Nigerian Ports Authority

## PUBLIC NOTICE

INDEPENDENCE CELEBRATIONS

CLOSURE OF PORTS

It is hereby notified for general information that the following ports will be closed on the dates shewn opposite them and that no port operations will take place at such ports on such dates:-

| PORT | TO BE CLOSED ON |
|---|---|
| Lagos | — 1st and 2nd October, 1960. |
| Port Harcourt | — 1st, 2nd and 10th October, 1960. |
| Other Ports | 1st and 2nd October, 1960. |

**Bayo Kehinde**
Secretary to the Authority.

N. P. A. Notice N0. 468
30th August, 1960.

## Awon Olopa Iwo-Orun Gba Owo Ominira.

IBADAN. A gbo irohin wipe awon Olopa oba ti o mbe ni Iwo-Orun gba owo ominira, owo osu kan asansile, nwon o si da pa-da ni osu mefa, diedie ni ososu.

Agbo wipe awon alase ti fi iwe ikede sode wipe, ki awon olopa ti o ba wu pe ki ijoba ya on ni owo osu kan na, ki o kowe wa.

Awon igbimo ilu Ibadan ti se ikede kakiri bi nwon o ti se ere ominira tiwon si. Iru ere ti nwon fe se yio je orisirisi ti eya ilu ti o mbe ni ipinle Iwo-Orun. Ere ti nwon fe se na, nwon fi si oro, yala ni Liberty Stadium ni yio gba ere na tabi odan ibiti nwon gbe nfi esin sare.

Orisirisi ere ni ti Yoruba, ti Ijesa, Ekiti, Kukuruku, Isan, Benin, Sekiri, Isobo, Asaba, ati Saki.

## Itan Adaba Ati Kolikoli

(Lati owo J. Ola Akande)

Nigba kan eiye Adaba ati Kolikoli je ore kori-ko-sun; ore won na po tobe ti opo enia fi npe won ni omo iya kanna. Ko han si Adaba wipe ore ti Kolikoli mba on se, ko de inu re.

"Ehinkule ni ota wa, ile ni aseni ngbe. Eniti a ni ka fi ehinti kamu didun osan, ganin-ganin lo nfun ni mu. Eniti a ni ko fe ni loju fi ata si enu" Ha! Edumare ko gbeni leke amoni-seni."

( Wo yoku loju ewe kejo )

INDEPENDENCE
is
NATIONAL
NATIONAL
BANK
is
INDEPENDENT

Congratulations
to
ALL NIGERIANS

# Omo'binrin To Nko Ise isegun Ti Oyinbo



Ọmọde'birin ti a nwo yi ni Omidan T. Odutọla tiṣe ọmọ bibi inu Oloye Odutọla nilu Ijẹbu-Ode, ti o lọ kọ iṣẹ iṣegun ti Oyinbo, Nigbati o nṣe idanwo ni Woolwich Polytechnic College ti Oludanwo rẹ Dr. L. Ellison duro ti gba gba gba, ti o nṣọ lọwọ lẹsẹ boya yio se aṣiṣe.




## AWON OLOPA NWADI ENI TI O KU SI ITA

A gbọ irohin wipe awọn ọlọpa ri oku ẹnikan ti o ku si Ọna pọ ita Mọṣalasi Olosun (Kings Street) oku na ko dojubaju ni ọdun mẹtadinlogbọn lọ. Orukọ eniti o ku na nje Oludotun Adewumi

Awọn ọlọpa sọ wipe apa oju ọgbẹ idapọ lara ologbe na. Ohun ti o wa ru awọn ọlọpa loju ni wipe ibikan ni nwọn sa ti pa ni ada yanna-yanna bayi ki awọn to wa gbe ju sinu kọrọ Kings Street lo jẹ ohun ti o si nru awọn ọlọpa loju

Ọlọpa kan boyi ni awọn ọlọpa rinna pe ti nwọn si nje itọpa ẹni ti o ṣe rẹ awọn ọlọpa ṣi mbẹ lenu iṣẹ ọrọ na nisisiyi ti nwọn ba si tun ti ridi ọrọ na si so ma yio si oju n leti. Olu ko fẹrẹ ku.

## Ijoba Egba Fe Tun Awon Eto Asogbo Se

Abẹokuta Alhaji D. S. Adegbenro ba awọn igbimọ Ẹgba damọran wipe ki nwọn tun eto awọn Aṣọgbo ti o mbẹ labẹ ijọba ibilẹ ṣe.

Awọn ijọba bilẹ Ẹgba ti faramọ eto ati imoran Alhaji D. S. Adegbenro lati tun gbogbo eto ti o ti wa nipa iṣẹ awọn Aṣọgbo ṣe, Igbimọ ibilẹ na yio si ṣe ididuro iṣẹ fun awọn Aṣọgbo ti o ti wa nibẹ fun ọjọ pipẹ, ṣugbọn ti awọn ko megiri si iṣẹ wọn, ti awọn ko si ja fafa to lenu iṣẹ wọn na.

Nwọn o tun ṣe idaduro lẹnu iṣẹ fun awọn ti nwọn ti ni akọsilẹ buruku, ati awọn oniwa palapala bawonni.

Ohun ti o fa sababi ti awọn Igbimọ ṣe fẹ ati gbọ ọrọ bẹ nipa irohin ti kun eti won wipe ọpọlọpọ awọn eniyan ti lọ ge igi ninu igbo laijẹ wipe awọn gba aṣẹ lodo igbimo.

Nwọn si ti nṣe mediwa lehin lati ma fi ọrọ ijoba tẹ lwe gbogbo aṣẹ laisiki ijoba mo.

Oloye E. O. Dosunmu ni alaga igbimo J. O. Osinyinola ni Akowe E. O. Awopetu S. O. Otun ati J. O. Obadina.

## Ogbeni Tarka Se Iranlowo Fun Ijoba

Gboko. Nigbati rogbodiyan ijagbọro kan fi bẹ silẹ ni Gboko ti o fi di ohun ti awọn ẹgbẹ kan fi ni lati ma fi ina kun ile awọn ẹgbẹ keji, a gbọ wipe Ogbeni J. S. Tarka lo ṣe iranlọwọ fun ijoba ti ọwọ ifi ba awọn eniyan na. Orukọ wọn ni wọnyi:-

Tereku Yuwa, Saor Achagh, Akwa Gbagh, Uke Akuzeed ati Use.

Nigbati awọn ko gbogbo wa dewaju adajọ, gbogbo wọn lo jẹbi, nwọn ko si ri ọrọ kan lati fi gba ara wọn silẹ. Adajọ na ṣa koko ẹwọn mọ wọn lara eyiti o lọ si ẹwọn ọdun mẹta wa nino, bẹẹ eyiti o lọ si ọdun mẹrun wa ninu wọn.

Ki adajọ to da ẹjọ fun won, o yin Ogbeni Tarka fun iranlọwọ ti o ṣeki ọwọ to tẹ awọn ọdaran na o sọ pe, o dara ki ijoba sowọpọ pẹlu rẹ.

Kere !o

Ati ni orisirisi egbogi fun arun Inarun ati arun Jẹdijẹdi, (Bitter Tonic Liquid of Life) Tete wa ra tirẹ, Ọkunrin ati Ọbinrin ki o to tan

J. A. AJAO BROTHERS

MEDICINE STORE

7, Egerton Road, Lagos.

# ELETI - OFE

ANJUWON KO ŞE WI L'EJO

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRA

28, Kosoko Street, Lagos. "ELETI - OFE, LAGOS

P. O. Box 467 Phone 23370

VOL. XII. NO. 495. SATURDAY OCT. 1, — OCT. 7, 1960


# AKO R'OHUN F'AYO . . . .

Ọpẹ l'ada; ọpọlọpọ ọpẹ mbẹ fun Ọlọrun Ọba Edumare, arinu-r'ode, olumọ ọkan, Ọba ti o nf'ola şiṣẹ fun ọjọ oni ti işe ọjọ kon-gbegue, ọjọ kini oşu October, ọdun 1960.

Melo-melo nina awọn enia pataki-pataki ti nwọn ti fi ara wọn, owo wọn wahala ati gbogbo igbesi aiye wọn şe işẹ ribiribi fun igbega ati idagbasoke orilẹ ede wa Nigeria yi, fun isọni-d'ominira kuro labẹ aşẹ ijọba ilẹ ajeji, ti pupọ awọn ẹni bẹ ko ni anfani ati fi oju ri ọjọ oni l'aye mọ aiye yi, ti nwọn ti rekọja si Isalu Ọwọn alakeji aremabọ.

Awa ti Ọlọrun dasi, ti o si fi ọjọ oni şe italọrẹ ola fun wa, ko si ohun ti a le şe ju ki a ma yin Ọlọrun l'ogo, ki a si ma fi ọpẹ fun orukọ mimọ Rẹ nigba-gbogbo, nitoripe iru ọjọ rere bi ọjọ oni ko tun ni waiye mọ.

A fi wosika wa yi ki gbogbo enyin ọkawe wa ọrẹ wa ati Onibara wa, nile, l'oko l'odo, ati gbogbo awọn ilẹ okere ti o ba jẹ ọmọ ilẹ Nigeria ku orire, ẹ ku ajabọ ajaga ilẹ ajeji kuro l'ọrun, ẹ si ku ayọ ainipẹkun fun ti ominira ilẹ ibi wa ti a ri ni ọjọ oni.

Ako r'ohun f'ayọ, ọpẹ l'ada o,

## Igbagbo Ko Wipe Ki A Ma Soro ile Eni

Ọba Oni ile Ifẹ jẹ Onigbagbọ, şugbọn igbagbọ ko di lọwọ lati şe oro ile ti o ba lọwọ awọn baba rẹ bẹni ko si pa aşa işẹdilẹ wọn rẹ. Ọba yi sọ fun Oniwe irohin kan wipe Onigbagbọ pataki ni on jẹ şugbọn ọpọlọpọ iyawo ni on ni, ipo on lo si jẹ ki on ni wọn bẹ nitoripe, bẹni on ba lọwọ awọn baba nla on.



Onigbagbọ paapa ni on jẹ şugbọn on gba Oduduwa ti o şe Iran baba nla on sile, on ko si gbọdọ maişe etutu rẹ, nitoripe ipo on ti lati şe bẹ. Ipo ati eto on ni ki on şe etutu si awọn irunmolẹ ti o şe pẹlu baba nla on, nitoriki aiye ma ba bajẹ.

Ko nşe ohun ẹtọ fun enia wipe ki o pa awọn ohun işedalẹ rẹ ti lai şe, nitori ki aiye ba le tutu fun oluwarẹ gbemu.

Ko nşe wipe gbogbo awọn Abọrişa ni ko gba Ọlọrun gbọ şugbọn gẹgẹbi awọn miran ti nfi St. Antoni. Iya Jesu, Angẹli Yisa, Angẹli Salu bẹ Ọlọrun, bẹna ni awọn Yoruba nfi Obatala, Orişa-oko bẹ Ọlọrun.

Nitoripe awọn ti nwọn mu isin ajeji wa si ẹdẹ wa fi kọ wa pe ọna ti awa ngba fi bẹ Ọlọrun ko dara şugbọn ki a ma gba ọna ti wọn wa o(nse) Ọlọrun. Sibẹ awọn ko fi ẹdọdo ona han wa nwon o si ma pe ni aşiri.

Awọn Oyinbo ni orişa pupọ ti nwọn nşe etutu si şugbọn nigbati isisi de nwọn mu mẹta dani ninu awọn orişa ti nwọn mbọ na, nwọn si şe leso. (1) Nwon mbo Olokun (2) Nwon mbo Aro igi (3) Nwon mbo awọn oku akoni ati awọn alagbara. Nwọn mọ ewo gbogbo awọn mẹtẹta yi ju ẹnikẹni lọ nwọn mọ ele ati ẹro rẹ.

Nigbati nwọn ba fẹ bọ awọn oku nwọn o pe ni ojo Iranti (Remembrance day).

(Wo yoku loju ewe keje)

## Ikini Ku Ayo Ominira

Olotu,

Jowo gba mi laye lati ki gbogbo awọn okawe Irohin Eleti - Ọfe Jakejado ilẹ Nigeria bakanna ni mo tun ki awọn Oşelu ilẹ wa pelu wipe, nwọn ku orire ti Ominira ti a bere loni

Mo bere kini Ominira na ri jẹ? Ohun ti o jasi ni wipe ki a fi imọ sokan ki a parapo sişe nile wa ki ale ki a ba le ni ilọsiwaju K'a fi otito sişe laişe are Mo ki nyin e ku ayo e ku ewu idaude, ki Ọlọrun jẹki a le lo ominira na pelu ayo ati alafia.

(Wo yoku loju ewe karun)


M.B.T.
(MAGIC BLOOD TONIC)
Ina de, okunkun parada. M.B.T. de, okunrun ṣo lo. Ẹjẹ dudu sare ogi pẹsẹsẹ. Ata buburu wo gba. Bile sun pẹkun-ẹkun. M.B.T. fọgun ẹjẹ ti amọ ni jeun b'ikan, amọ ni igbọbe bi ọkun. amọ ni tọ bi akere. A biwere f'aboyun, agbe jẹda powon abiyamọ Ahọn-dudu, ẹsẹ-wiwu, ati ara-jija ko ni fẹnifi nio o.
ipa phlu ipa owo-ọkọ.
ARADAN STORES P.O.Box?
EBUTE-METTA.


# Alhaja Oluwa Di Iya Suna Eko

EKO. Alhaja Ayisatu ti işe iyawo Ologbe Alhaji Tijani Oloye Iman ti ilu Eko ni awon Jamme Alasalatu fi jẹ Oloye gbogbo awọn Iya suna ilu Eko ninu Moşalaşi nla ti ilu Eko lọjọ ẹti to koja.

A gbọ wipe iya to bi Alhaja Ayisatu ti a darukọ yi l'ẹni ti o ti kọ jẹ oye ti nwon gbe fun ọmọ rẹ yi ni ilu Eko.

Awọn ti miran ti nwon tun fi jẹ oye lọjọ na ni Alhaja Rabiatu Iyalode ti nwon fi jẹ oye Olori awon Iya Adini Eko ati Iyafin Sadia Balogun jẹ oye olori awon Balogun Alasalatu ti ilu Eko.

A gbo wipe lojo na, ati gbogbo awon Iya Adini Eko awon Iya Suna Eko ati gbogbo awon Alasalatu lo pe jọ si Moşalaşi nla lojo ti nwon ... oye wonyi, ile kun ọua bọ.

Oye ka a muri o




# Olopa Mu Omo Kekere Kan Fun Esun Apania

ONITSHA. Omode kekere kan ti ko ju omo odun metadilogun lo, ni awon olopa lo tamu ni akata iya re fun esun wipe on lo pa omodekunrin kan ti ko ju omo ogun odun lo ti awon npe oruko re ni Okafo Okere.

Okafo Okere atijomo ti o paa yi jijo ase ise lodo enikanna sugbon ija de larin awon mejeji eyiti o di ohun ti Okafo fi ku sinu ija na.

Awon olopa ti mu omode na si ihimole, awon s mbe lesu iwadi nisisiyi. Bi a ba ti tun gbo oro na si ao ma yin si nyin leti.

## Oba Adele Ki Omoba Gesi Ku Abo

'Alaiyeluwa Oba Adeniji Adele Keji ti ise Baba egbe fun Igbimo Lagos Town Council so wipe, nigbati yio ba fi to oganjo oru ojo Jimo mojumo ojo Saturday, Asia Gesi ti o ti nfe lele lori ile Nigeria, yio di fifa wale, lehin iwon ogorun odun, ti o ti bere si joba lori wa



ao si gbe asia omnira ... Nigeria ... ni ipo re, sugbon awon ara ilu Eko ko ni gbagbe Gesi gegebi baba wa.

Oro nwonyi je ara eyiti Alaiyeluwa Oba Adele fi ki omoba Alexandra wipe ki o ma wole. O ni a ko ni gbagbe ojo rere na lodun 1956 nigbati Alaiyeluwa Elisabeti Keji, Oba Gesi fi wa se abewo wa nile Nigeria. Bakanna ni abewo ti Omoba Alexandra yi yio je koni gbagbe.

Gbogbo wa lo ti fi eti leko, ti o si ti gbo irohin nipa irin ajo re ti o rin lo sile Australia ni esi, gegebi o ti lariarin to bakanna ni a ni reti wipe, irin ajo re ti odun ni wa sile Nigeria yio lariarin pelu.

## IKINI KU AYO OMINIRA

(... loju ewe kerin)

Mo ki enyin ara ile Nigeria ... e ku orire ki ... ipo lehin ... N'sise ... ati ... Ominira wa, ... Ominira wa na ... parire s'ogba ... (Pr... yard) sugbon ... gbeleke Ogo ... odumare.

## ELETI-OFE D'ARABA

CARSON PAINTS AND VANISHES



SOLD AGENTS
IKORODU TRADING COMPANY
20, & 28, Balogun Street, Lagos.

## Eniti Ko Gbo Duru Ki Jo Duke

Nwọn fẹ jo ibi nla kan fun awọn Adiri ati Odi lati fi wa owo iranlọwọ fun ẹgbẹ wọn.

Gbogbo awọn Ayadi ati Adiri ilu na ni nwọn pe lati wa ba wọn jo papọ.

Nina awọn eniti nwọn fi iwe pe ni Ọgbẹni Kuro ati Iyawo rẹ wa. Nigbati nwọn nlọ sibi ijo Ọgbẹni Kuro sọ fun Iyawo rẹ pe kini ẹnia ti pe le ba adiri sọrọ pe ki o wa jo? Iyawo rẹ dahun pe eyini ko poco, iwọ sa duro nibẹ̀ rẹ rerin si ki o si tẹriba yio dide tele ọ.

Nitorọ nigbati nwọn de ibijo, Ọgbẹni Kuro ri ọkan ti o dara ti o si lẹwa ninu awọn Adiri, o duro niwaju rẹ o rẹrin o tẹriba a si nọwọ si i o si bere si gba. Ijo titi nigb o adiri na ko jẹ ti Ọgbẹni Kuro ri ayẹ lọ ba, ọlomiran jo.

Nigbati ara ja Iyawo rẹ o lọ ba ọkọ rẹ nibiti ẹnjo n se fun pe ionigba ti a ti de ibiu, iwọ Koiti wa bami jo ki lo diẹ, ọwọ? O dahun o wi fun Iyawo rẹ pe obinrin adiri ni ko ma fi mi silẹ nko a mọ bi a ti se ayọ fun wọn, Erin, ha ha ha ha.

*Always ask for* **'DE FACTO'** *the bread with the appetising flavour*

Plushes, Velvet, Velveteens Damask & Building Materials

PLEASE CONSULT

**Okunowo Brothers**

62, Massey Street. (Ẹja Market)

LAGOS, NIGERIA.

TheHouse where Courtesy & Satisfaction are Guaranteed.




## Awon Gbajumo Meta Wo Ijogbon Ejo Kotu

EKO. A gbo irohin wipe awọn gbajumo enia meta nwọnyi lu ijogbon ejo kotu Samel Mogbede Ajululagba ti iṣe akowe fun Banks Store ati Shitta Alabi dereba Banks, ati Lamidi Savage, dereba Banks Store. Awọn meteta nwọnyi ni awọn olọpa ka mọn mejidilogbon mo loruni wipe nwọn jale nwọn si yi iwe pada.

Awọn meteta ti a darukọ nwọnyi jẹ gbajumo nilu Eko, ti nwọn si nṣe iṣẹ labẹ Banks Transport Service, nwọn ji egbaa le okowo lorugba apo Simanti ti apapo iṣe owo rẹ je egberun Poun lowo awọn oyinbo Ọlowo ni Apapa.

Nigbati adajọ bere lọwọ awọn odaran na wipe nwọn jebi tabi nwọn ko jebi? Gbogbo wọn dahun pe rara! awọn ko jebi. Ni adajọ ba fi wọn pamọ si itimole, ọwọn ko si gba idaro fun wọn sugbọn adajọ fi ojo igbejọ wọn si ọsu October 18th ati 19th. 1960. ninu Kotu Yaba.

## ỌKUNRIN KAN RO ARA RẸ PIN O GBE IBỌN JẸ

MUSHIN. Irohin ti o gbọjukan lojo Jimọ kan nilu yi ni wipe, ẹfan alyi tabi edi fun ọkunrin kan ti o nda ẹmu lona Idi Araba leti Mushin ti o fi ro gbogbo igbesi aiye re pin, ti o si fi gbe ibọn ṣakabula jẹ wamu lẹkanna.

Nigbati awọn Oniwe irohin lọ wadi wo lọdọ ọga Olọpa nipa iku ọkunrin ẹl mu na, Ọga olọpa na fesi dahun wipe ọjọ ti o dele yi yato. Bi ara ọjọ hayi ba dele ko nṣe oro ẹnikan nitoripe on funrarẹ lo pa ara re ko nṣe ẹnikan lo la pa.

A gbo wipe ọkunrin na fi owo ara re ta ẹni o dasole le l-ri o si fi ese re fa oko ibọn eyiti o ran a si ọrun alakeji aranabo.

Nwọn gbe oku rẹ ninu agbara dẹ ly si ikẹjo, n na ile alaisan fun ayẹwo.

# NIGERIAN RAILWAY CORPORATION

## INDEPENDENCE CELEBRATIONS

### SPECIAL PASSENGER TRAINS

The following Special passenger trains will be provided during the Independence Celebrations:-

(a) AGEGE—LAGOS TERMINUS—AGEGE
26TH SEPTEMBER—4TH OCTOBER 1960

To convey Third Class Accommodation only:

| | | | | | | | |
|---|---|---|---|---|---|---|---|
| Agege | Dep. | 7.15 | a.m. | Lagos Terminus | Dep. | 10.50 | a.m |
| Ikeja | " | 7.23 | " | Ebute Metta | " | 10.59 | " |
| Sogunle | " | 7.28 | " | EB. Junction | " | 11.07 | " |
| Oshodi | " | 7.37 | " | Yaba | " | 11.14 | " |
| Mushin | " | 7.45 | " | Mushin | " | 11.25 | " |
| Yaba | " | 7.53 | " | Oshodi | " | 11.37 | " |
| EB. Junction | " | 8.01 | " | Shogunle | " | 11.43 | " |
| Ebute Metta | " | 8.10 | " | Ikeja | " | 11.50 | " |
| Lagos Terminus | Arr. | 8.15 | " | Agege | Arr. | 11.57 | " |
| Agege | Dep. | 1.05 | p.m | Lagos Terminus | Dep. | 10.00 | p.m |
| Ikeja | " | 1.18 | " | Ebute Metta | " | 10.08 | " |
| Shogunle | " | 1.23 | " | EB. Junction | " | 10.16 | " |
| Oshodi | " | 1.33 | " | Yaba | " | 10.22 | " |
| Mushin | " | 1.39 | " | Mushin | " | 10.34 | " |
| Yaba | " | 1.47 | " | Oshodi | " | 10.42 | " |
| EB. Junction | " | 1.55 | " | Shogunle | " | 10.48 | " |
| Ebute Metta | " | 2.03 | " | Ikeja | " | 10.55 | " |
| Lagos Terminus | Arr. | 2.10 | " | Agege | arr | 11.03 | " |

(b) IBADAN LAGOS TERMINUS—IBADAN
30TH SEPTEMBER—2ND OCTOBER 1960

To convey all classes of accommodation:

| | | | | | | | |
|---|---|---|---|---|---|---|---|
| Ibadan | Dep. | 6.50 | a.m. | Lagos Terminus | Dep. | 10.45 | p.m |
| Olokemeji | " | 8.10 | " | Itori | " | 00.18 | a.m |
| Abeokuta | " | 9.30 | " | Abeokuta | " | 1.17 | " |
| Itori | " | 10.30 | " | Olokemeji | " | 2.31 | " |
| Lagos Terminus | Arr. | 11.55 | " | Ibadan | Arr. | 4.00 | " |

(c) ABEOKUTA—IBADAN—ABEOKUTA
30TH SEPTEMBER—2ND OCTOBER 1960

To convey all class of accommodation:

| | | | | | | | |
|---|---|---|---|---|---|---|---|
| Abeokuta | Dep. | 7.10 | a.m. | Ibadan | Dep. | 7.10 | p.m |
| Arikola | " | 7.28 | | Adio | " | 7.36 | " |
| Sanusi | " | 7.44 | | Ilugun | " | 7.59 | " |
| Ashipa | " | 8.04 | | Ogunshile | " | 8.20 | " |
| Eruwa Road | " | 8.23 | | Olokemeji | " | 8.40 | " |
| Olokemeji | " | 8.44 | | Eruwa Road | " | 8.53 | " |
| Ogunshile | " | 8.55 | | Ashipa | " | 9.06 | " |
| Ilugun | " | 9.19 | | Sanusi | " | 9.31 | " |
| Adio | " | 9.42 | | Arikola | " | 9.58 | " |
| Ibadan | Arr | 10.15 | | Abeokuta | Arr | 10.15 | " |

**FARES**: The existing normal reduced passenger fares will apply. Please contact your Station Master for details

THERE'S FREEDOM IN TRAIN TRAVEL

# E KU AYO OMINIRA


## Awon Osise Reluwe Kowe Si Olotu Ijoba

EKO. Awon Osise Reluwe kowe ranse si Alhaji Sir Abu Bakar Tafawa Balewa ti ise olotu Ijoba Alapapose wipe, ohun edun okan lo je fun won nigbati awon olotu eto Ominira fi oju fo awon osise Reluwe da, ti nwon ko fi iwe ipe ranse si awon osise na lati wa fi woran nipari osu September, 1960.

Akowe awon Osise na so pe ko nse awon egbebi awon osise Reluwe lo ye ki awon eleto Ominira fi oju fo da, o ye ki Ijoba ka awon egbe si gegebi nwon ti nse ni gbogbo agbaiye.

## IGBAGBO KO WIPE KI A MA SE ORO ILE ENI
( O bere loju ewe kerin )

A gbo wipe ibukun ni fun iranti awon Olododo nitoripe awon Angeli Olorun yio ma gbadura fun eni na.

Nigbati awon ba fe bo ako igi bo ti wu ki igi na di won lowo to kaka ki nwon ge nse ni nwon o ro laso ko nse wipe nwon o ra aso gidi fun, nwon o kan mo lara, bi be ko nwon o ye ona si apa ibomiran nwon o si fun igi na laye, nitoriki iku ma ba po larin ilu. Nwon o fi efun funfun yida, gegebi eyiti nwon roso fun u.

Eketa ni igbati nwon ba fe bo Olokun, awon oko nlanla ti nwon nkoja larin okun, nigbati nwon ba de ibiti awon eranmi gbe po, nwon o ma da onje sinu omi fun won ni sise bayi, Olokun a ma gbe won nigba pupo.

Nitorina, bi ogun ba de awon Gesi ko lagbara tobe lori ile, sugbon bi nwon ba bo si arin okun, ko si eniti o le la arin won koja ti ko ni ri sinu omi. Eyi ni da won loju ju ada lo.

## Awon Alejo To Wa Ba Wa Se Ominira Nilu Eko

Awọn ti a to orukọ wọn sinu iwe irohin yi jẹ diẹ ninu awọn enia pataki ti o ti ilu ọọn wa lati ba wa yọ ayọ ti ominira nilu Eko.

1 Alhaji Sir Amodu Bello, ti işe Sarduna Şokoto ti o si tun jẹ aşiwaju awọn oselu ni ipinlẹ Oke-Ọya.

2 Eniti a tun gbọ wipe o tun de silu Eko lati ọna Oke-Ọya wa ni Mallam Ibrahim Imam.

3 Ọgbeni E.C. Gram ti işe Adele Alaga oyinbo Elepo (Mobil Oil Co.)
4. Ọgbeni F.W. Barcleft alaga igbimọ Socony oil Co.

5 Ọgbeni William Tolbert Adele Baba ọgbe ilu Liberia.

6. Awọn enia meji lati ilẹ Japan Ọgbeni Konching Cinsi ati Fengjeng Len.
7 Ọgbeni Julius Nyerere ti işe aşiwaju awọn oselu nilẹ Tangayika wa ba wa yọ ayọ ominira.

8 Ọgbeni E.R.T. Nyumuleye Hkumor ba ọkọ ofurufu gunle si Ikeja fun ti ominira.

9 Olọla Jean Maury Archbishop of Laodicea de silẹ Nigeria gẹgẹbi asoju ilu Rome ati Ijọ Aguda ti o wa nilẹ Nigeria.

---

## Itan Adaba Ati Kolikoli

(O bẹrẹ loju ewe keji)
(Lati ọwọ J. Ọla Akande)

Ni ọjọ kan, adaba pe Kolikoli pe ki o jeki nwọn lọ pa eja. O si dahun pe, o ya, jẹ ki a lọ. Adaba mu ọbẹ ati ada dani, Kolikoli mu igba ati ano dani. Nigbati nwọn de odo adaba bọra silẹ, Kolikoli na si bọ tirẹ pelu, nwọn si bẹrẹ si gbọn odo titi nwọn fi gbọn gbẹ.

Adaba lọ koko ri eja kan pa ti o tobi, nwọn si ri eja wẹrẹ bi ogoji pa pelu. Gbogbo ero Kolikoli nipe ki gbogbo eja sa jẹ ti on nikan bẹni ija bẹrẹ larin awọn ọrẹ mejeji na. Kolikoli si nfẹ ko gbogbo eja na lọ.

Ibẹ ni Adaba ti fo sori igi, o nwipe "Gbogbe-gbomamu" Kolikoli paapa gbera o di ori igi, o nwipe iwọ adaba "ku ku gba a tan, kuku gba a tan".

Nigbati adaba ri eyi, lo ba fi ọrẹ rẹ sibẹ, o si ba tirẹ lọ. Kolikoli woye wipe, adaba fi on silẹ o ko eja silẹ le on lọwọ, loba ko gbogbo eja na lọ silẹ rẹ o şe gbogbo rẹ, o si jẹ ẹ.

Lati ọjọ na wa ni adaba ti nke bayi nigbati o ba ri Kolikoli lokere wipe
Gbogbo ẹ, gbo ẹ
nia mu.

---

## ADURA FUN OMINIRA

OLOTU.
Jọwọ gba mi laye lati fi ọrọ kekere yi si eti igbọ awọn okawe Eleti-Ọfe rẹ yi. Ọrọ na nipe, awa Aladura CHURCH OF THE LORD ti şe eto adura ọjọ meta fun ti Ominira wa (pẹlu awẹ), eyi ti yio bẹrẹ ni ọjọ kejidinlogbọn osu yi, yio si pari ni gbọn'jọ osu yi kanna.

Eto asiko adura na lo bayi:
September 28...... 9.00 p.m.
September 29...... 6.00 p.m.
September 30...... 6.00 p.m.

Ki Oluwa jẹki Ominira na rọ gbogbo wa o (Amin) Modupe aye ti e gba mi o. Ọkọ Ọba koni sa yin l'esẹ o.

Ti yin toto.
Bishop M. S. Gbogboade,
Alamọjuto awọn Ijọ Church of the Lord ni Eko ati Agbegbe rẹ.

Bata

SHOE CO. NIGERIA LTD.

CONGRATULATES THE GOVERNMENTS AND THE PEOPLE OF THE FEDERATION OF NIGERIA ON THE ATTAINMENT OF INDEPENDENCE ON OCTOBER 1, 1960.

Manufacturers and Importers of Shoes and Exporters of raw rubber.

Bata SHOEMAKERS TO THE WORLD

HEAD OFFICE, 81—87 BROAD STREET, LAGOS.
FACTORY AT APAPA
Branches throughout Nigeria.